Kí Ni Kò Sí Nínú Àwòrán Yìí?

Ka Òwe 18:10 àti 26:17. Kó o sì wo àwòrán yìí. Àwọn nǹkan wo ni kò sí nínú àwòrán náà? Kọ ìdáhùn rẹ sórí ìlà tó wà nísàlẹ̀ yìí, kó o fi àwọn àmì tó-tò-tó tó wà níbẹ̀ ya èyí tó kù lára àwòrán náà, kó o wá kùn ún.

1 .....

2 .....







FÚN ÌJÍRÒRÒ: Kí lo rí kọ́ nínú àwọn ẹsẹ Ìwé Mímọ́ yìí? Ṣé téèyàn bá ti mọ orúkọ Ọlọ́run, ó ti rí ojú rere Ọlọ́run nì-yẹn? AMỌ̀NÀ: Ka Sáàmù 91:2; Òwe 3:5, 6. Kí nìdí tí kò fi yẹ ká máa yọjú sí ọ̀rọ̀ ọlọ́rọ̀? AMỌ̀NÀ: Ka Gálátíà 6:5-7; 1 Tẹsalóníkà 4:11; 1 Pétérù 4:15. Léyìn náà, ka Òwe 26:18, 19. Ṣé ó burú kéèyàn máa dápàárá rírùn? AMỌ̀NÀ: Ka Òwe 14:13; 15:21; Mátíù 7:12.

KÍ ÌDÍLÉ ṢE É PA PỌ̀: Ẹ ka Òwe 31:10-31 pa pọ̀. Kí ẹnì kan nínú ìdílé fara ṣàpèjúwe bí obìnrin tó dáńgájíá ṣe máa ń hùwà gẹ́gẹ́ bí ẹsẹ Bíbélì yẹn ṣe sọ. Kí ẹni yẹn má sọ̀rọ̀. Káwọn tó kù nínú ìdílé sọ ohun tí ẹni yẹn ń ṣe. Ẹ jíròrò àwọn ohun tẹ́ ẹ tún lè ṣe láti túbọ̀ dáńgájíá.

Tó o bá fẹ́ tẹ àwọn ẹ̀dà míì jáde lára "Àtúnyẹ̀wò fún Ìdílé," lọ sí ìkànnì **www.jw.org/yo**

1. Ilé ìsọ́ aláǵbára. **2.** Ajá.

www.jw.org © 2011 Watch Tower Bible and Tract Society of Pennsylvania